# TAN' T' ỌLỌRUN

NIPA

A. K. AJIṢAFẸ

PRINTED BY
THE IFE-OLU PRINTING WORKS
31, Kakawa Street—P. O. Box 756.
LAGOS, NIGERIA

# AKIYESI

ẸNITI o ṣe iwe yi ko ṣe e nitoripe iwa rẹ dara a ko ri iru rẹ ri. A tilẹ le sọ pe iwa rẹ buru a ko ri iru rẹ ri.

Nigba pupọ li awa a ma sọ wipe awọn oniwasu gbigbona tabi awọn oniwe to kun fun ẹkọ rere ko nhuwa rere gẹgẹ bi iwasu tabi ẹkọ rere wọn. Ọran itiju li eyi jasi ṣugbọn o fi dara ni. Eyi fihan pe Ọlọrun nikan lo pe ati pe laisi Ọre-ọfẹ Rẹ ko si ohun ti ẹnikan jamọ. O yẹ ki eyi tubọ fun ni lagbara ati itara lati ma ṣi ara ẹni leti; o si yẹ ki ẹniti a nṣi leti ki o tubọ ma ronu ki o sima ṣọra nigbagbogbo pelu adura.

O ko gbọ bi Paulu Apostili ti wi? O ni. "Ẹ ba mi gbadura pe lẹhin gbogbo iwasu mi ki emi na ki o maṣe di ẹni itanu kuro lọdọ Ọlọrun.

Akoko yi jasi akoko ti a le wipe "omi aye ru. Ọbẹ aiye kan" nitoripe ko si ibiti awọn ko nko adie alẹ nisisiyi nipa ode lile. Nitorina ni mo ṣe gbidanwo lati kọ iwe yi lati fi itunu fun ẹniti ọkan rẹ mbajẹ; ireti fun olupọnju; iṣiti ati ikilọ fun alaironu ati adagbamadanu: nitoripe titi o fi di oni oloni ọpọlọpọ koi ti mọ pe Ọlọrun mba araiye wi. Ọpọlọpọ lo si mbẹ ti o jẹpe kaka ki ohun ti wọn nri mu wọn sunmọ Ọlọrun, nwọn tubọ njina si i ni.

Bi iwe kekere yi ba mu ọ fẹ Ọlọrun li *afetan* ti o si mu o gbe Orukọ Rẹ ga nipokipo ti o wu ki o wa, njẹ wahala ati ajo mi ko lọ si asan ṣugbọn Iyin ati Ogo na jẹ ti Ọlọrun.

Njẹ iwọ ti yio ka iwe yi adura mi fun ọ ni pe ki Ọlọrun ki o maṣai jẹ ki o mọ on ju ohun gbogbo lọ. Ki On ki o si ṣe atubọtan rẹ ni rere fun ọ nipati ẹmi ati nipati ara. Amin.

Emi ni olufẹ rẹ toto,
A. K. AJIṢAFẸ.

*Nigeria,*
*November* 13, 1919.

## IFIJUBA

Fun Ogo Ọlọrun ati fun imọ agbara ati titobi Rẹ,

Kiyesi i, Ọlọrun tobi awa kosi mọ bi O ti tobi to !—*Jobu* 36, 26.

A. K. AJIṢAFẸ.

*January*, 1921.